


Láti ọwọ́ Ààrẹ Thomas S. Monson

# Jíròrò Ipa Ọ̀nà Ẹsẹ̀ Rẹ

*Bí a ṣe ńwo Jésù bí Alápẹrẹ wa àti bí a ṣe ńtẹ̀lé àwọn ìṣísẹ̀ Rẹ̀, a lè padà láìléwu sí ọ̀dọ̀ Bàbá wa Ọ̀run.*

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi ọ̀wọ́n, mo ní ìrẹ̀lẹ̀ bí mo ti dúró níwájú yín ní ààrọ̀ yí. Mo bèèrè fún ìgbàgbọ́ yín àti àdúrà fún mi bí mo ṣe ńṣe àbápín ọ̀rọ̀ mi pẹ̀lú yín.

Gbogbo wa bẹ̀rẹ̀ ìrìnàjò pàtàkì àti ìyanu nígbàtí a kúrò ní ayé ẹ̀mí tí a sì wọ inú ìpeníjà ìgbàkúgbà ti ìpele yí tí à ńpè ní ayé ikú. Àwọn àkọ́bẹ̀rẹ̀ èrèdí wíwà lórí ilẹ̀ ayé wa ni láti gba ara ti ẹran àti egungun, láti ní ìrírí tí ó le wá nípasẹ̀ yíyapa kúrò lọ́dọ̀ àwọn òbí wa ọ̀run nìkan, àti láti rìi bí àwa yíò pa àwọn òfin mọ́. Nínú ìwé ti Ábráhámù, orí kẹ́ta a kàá pé: "A ó dán wọn wò níbí pẹ̀lú, láti ri boyá wọn yíò ṣe gbogbo àwọn ohun èyíkéyí tí Olúwa Ọlọ́run wọn yíò paláṣẹ fún wọn."[1]

Nígbàtí a wá sí ilẹ̀ ayé, a mú ẹ̀bùn ńlá náà wá pẹ̀lú wa láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run — àní agbára láti yàn fún ara wa. Ní ẹgbẹẹgbẹ̀rún àwọn ọ̀nà ni a ti ní ànfàní láti yàn fúnra wa. Níhìn yìí a kọ́ láti ọ̀dọ̀ ọgá oníṣẹ́ líle ti ìrírí. À ńmọ̀yàtọ̀ láàrín ire àti ibi. À ńṣe ìyàtọ̀ bí ìkorò àti adùn ṣe rí. À kọ́ pé àwọn ìpinnu máa nyọrí sí ìpín.

Ó dámi lójú pé a kúrò ní ọ̀dọ̀ bàbá wa pẹ̀lú ìbòmọ́lẹ̀ ìfẹ́ kan láti padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀, pé kí lè jèrè ìgbéga náà tí Ó ṣètò fún wa, èyí tí àwa fúnrawa sì ńfẹ́ gàn an. Bí ó tilẹ̀ jẹ́pé a fi wá sílẹ̀ láti ṣe àwárí àti láti tẹ̀lé ipá ọ̀nà náà èyítí yíò darí wa padà sí ọ̀dọ̀ Bàbá ní Ọ̀run, Òun kò ránwa sí ìhínyìí láì sí ìdarí àti ìtọ́sọ́nà. Kàkà bẹ́ẹ̀, Ó ti fún wa ní àwọn ohun èlò tí a nílò, àti pé Òun yíò tìwálẹ́hìn bí a ṣe ńwá ìrànlọ́wọ́ Rẹ̀ tí a sì ńtiraka láti ṣe gbogbo ohun tí a ní agbára láti faradà títí dé òpin àti latii ní ìyè ayérayé.

Láti ṣe ìrànwọ́ tọ́ wa sọ́nà a ní àwọn ọ̀rọ̀ Ọlọ́run àti ti Ọmọ Rẹ̀ tí a rí nínú àwọn ìwé mímọ́ wa. A ní ìmọ̀ràn àti àwọn ẹ̀kọ́ ti àwọn wòlíì Ọlọ́run. Ní jíjẹ́ pàtàkì tí ó tayọ, wọ́n ti pèsè wa pẹ̀lú àpẹrẹ pípé kan láti tẹ̀lé—àní àpẹrẹ ti Olúwa àti Olùgbàlà wa, Jésù Krístì— wọ́n sì ti fún wa ní àṣẹ láti tẹ̀lé àpẹrẹ náà. Olùgbàlà Fúnrarẹ̀ sọ pé: "Wá, tẹ̀lé mi."[2] "Àwọn iṣẹ́ náà èyí tí ẹ rí ti emi ńṣe òun ni kí ẹ̀yin ṣe bakannáà."[3] Ó ju ìbèèrè náà, "Irú ènìyàn wo ni ó yẹ kí ẹ jẹ́?" Nígbànáà Ó dáhùn, "Lóótọ́ ni mo wí fún yin, àní bí èmi ṣe jẹ́."[4] "Ó la ipa ọ̀nà ó sì ṣíwájú ní ọ̀nà náà."[5]

Bí a ṣe ńwo Jésù bí Alápẹrẹ wa tí a sì ńtẹ̀lé ìṣísẹ̀ Rẹ̀, a lè padà láìléwu sí ọ̀dọ̀ Bàbá wa Ọ̀run láti gbé pẹ̀lú Rẹ̀ títíláé. Wòlíì Nífáì sọ pé, "Bíkòṣepé, ènìyàn bá ní ìfaradà dé òpin, ní títẹ̀lé àpẹrẹ ti Ọmọ Ọlọ́run alààyè, òun kò lè ní ìgbàlà."[6]

Obìnrin kan, ní ìgbà kọ̀ọ̀kan tí ó bá ńsọ àwọn ìrírí tí ó ní ní ásìkò ìbẹ̀wò kan sí Ilẹ̀ Mímọ́, yíò kígbe sókè, "mo ti rìn níbi tí Jésù ti rìn!"

Ó ti wà ní itòsí íbi tí Jésù ti gbé tí ó sì kọ́ni. Bóyá ó dúró lórí àpáta lórí èyí tí Ó ti fi ìgbà kan dúró tàbí wo títò òkè tí Òun ti bojú wo orí rẹ̀ nígbàkàn rí. Àwọn ìrírí, nínú àti níti ara wọn, jẹ́ aládùn sí I; ṣùgbọ́n rírìn ní ti ara ***níbi tí*** Jésù ti rìn kò ṣe pàtàkì tó rírìn ***bí*** Òun ti rìn. Ṣíṣe bí ìṣe Rẹ̀ àti títẹ̀lé àpẹrẹ Rẹ̀ ṣe pàtàkì ju títiraka láti ṣe àtúnrìn ìyókù àwọn ojú ipa ọ̀nà tí Ó rékọjá ní ayé ikú.

Nígbàtí Jésù nawọ́ ìpè sí ọkùnrin ọlọ́rọ̀ kan pé, Wá, tẹ̀lé mi, ,"[7] Kò gbìrò lásán pé kí ọkùnrin ọlọ́rọ̀ náà tẹ̀lé Òun lọ sókè àti sílẹ̀ àwọn òkè àti àfonífojì ti ìletò.

A kò nílò àti rìn ní etí bèbè Gálílì tàbí láárín àwọn òkè Jùdéà láti rìn níbi tí Jésù rìn. Gbogbo wa lè rìn ní ipá ọ̀nà tí Ó rìn nígbàtí, pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ ní dídún léti wa, ẹ̀mí Rẹ̀ ní kíkún ọkàn wa, àti àwọn ìkọ́ni rẹ̀ ní ṣíṣe atọ́nà sí ìgbé ayé wa, a yàn láti tẹ̀lé E bí a ṣe ńrìn ìrìn àjò nínú ayé ikú. Àpẹrẹ Rẹ̀ ńtàn ìmọ́lẹ̀ sí ọ̀nà. Ó sọ pé, "Èmi ni ọ̀nà, òtítọ́, àti ìyè."[8]

Bí a ṣe ńyẹ ọ̀nà tí Jésù rìn wò, a ó rìi pé ó mú U la ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìpèníjà já irú kannáà tí àwa fúnra wa yíò dojúkọ láyé.

Fún àpẹrẹ, Jésù rìn ní ipá ọ̀nà ìjákulẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ó ní ìrírí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìjákulẹ̀, ọ̀kan lára àwọn tí ó dunni jù ni wọ́n ṣe àpèjúwe nínú ìpohùnréré

Rẹ̀ lórí Jérúsálẹ́mù bí Ó ṣe parí iṣẹ́ ìránṣẹ́ ìta gbangba Rẹ̀. Àwọn ọmọ Ísráẹ́lì ti kọ ààbò apá ìdáàbòbò èyí tí Ó fi fún wọn. Àwọn ọmọ Ísráẹ́lì ti kọ ààbò apá ìdáàbòbò èyí tí Ó fi fún wọn. Nínú ìrora Ó kígbe sókè, "Jérúsálẹ́mù, Jérúsálẹ́mù, iwọ tí ó pa àwọn wòlíì, tí ó sì sọ òkúta lù àwọn tí a rán sí ọ pa; nígbà mélo ni emi nfẹ́ íràdọ̀ bò àwọn ọmọ rẹ, bí àgbébọ̀ ti íràdọ̀ bo awọn ọmọ rẹ̀ lábẹ́ apá rẹ̀, ṣùgbọ́n ẹ̀yin kò sì fẹ́!"[9]

Jésù rìn ní ipá ọ̀nà àdánwò. Lúcífà, ẹni ibi náà, kó agbára ńlá rẹ̀ jọ, ẹ̀tàn rẹ̀ tí ó wuni jù, dán An wò ẹni náà tí ó ti gbààwẹ̀ fún ogójì ọ̀sán àti ogójì òru. Jésù kò juwọ́ sílẹ̀; kàkà bẹ́ẹ̀, Ó tako àdánwò kọ̀ọ̀kan. Àwọn ọ̀rọ̀ ìpínyà Rẹ̀. "Padà lẹ́hìn mi, Sátánì."[10]

Jésù rin ipa ọ̀nà ìrora. Gba Gẹ́thsémánì rò, níbití Ó ti wà "nínú ìrora kan . . . àti òógun rẹ̀ sì dàbí ìró ẹ̀jẹ̀ nlá, ó ńkán sílẹ̀."[11] Kò sí ẹnikan tí ó lè gbàgbé ìjìyà Rẹ lórí àgbélèbú oró.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan wa yíò rin ipa ọ̀nà ìjákulẹ̀, bóyá nítorí ànfàní kan tí ó sọnù, agbára kan ṣíṣìlò, àwọn ohun tí olólùfẹ́ kan ti yàn, tàbí yíyàn tí a ti ṣe fúnra wa. Ipa ti àdánwò bákannáà yíò jẹ́ ipa ti ẹnìkọ̀ọ̀kan. A kàá nínú ìpín kọkàndínlọ́gbọ́n ti Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú : "Àti pé ó gbọ́dọ̀ jẹ́ pé èṣù yíò dán àwọn ọmọ ènìyàn wò, tàbí wọn kò ní jẹ́ aṣojúẹni fúnra wọn."[12]

Bákannáà ni a ó rìn ní ipa ọ̀nà ìrora. Àwa, bíi ìránṣẹ́, kò lè Nírètí ju Ọ̀gá náà, ẹni tí ó fi ayé ikú sílẹ̀ lẹ́hìn ìrora ńlá àti ìjìyà níkan.

Nígbàtí àwa yíò rí ìkorò ìbànújẹ́ ní ipa ọ̀nà wa, a lè rí ìdùnnú ńlá bákannáà.

Àwa, pẹ̀lú Jésù, lè rìn ní ipa ọ̀nà ti ìgbọràn. Kò ní rọrùn nígbàgbogbo, ṣùgbọ́n ẹ jẹ́ kí ọ̀rọ̀ àkọmọ̀nà wa jẹ́ ogún tí a gbà láti ọwọ́ Sámúẹ́lì: "Kíyèsi, ìgbọ́ran sàn ju ẹbọ, ati ìfetísílẹ̀ sì ju ọ̀rá àgbò."[13] Ẹ jẹ́ kí a rántí pé ìparí àyọrísí ti àìgbọràn ni ìgbèkùn àti ikú, nígbàtí èrè fún ìgbọràn jẹ́ òmìnira àti ìyè ayérayé.

Àwa, bíi Jésù, lè rìn ní ipa iṣẹ́ ìsìn. Gẹ́gẹ́bí ẹwà dídán ìmọ́lẹ̀ ti ìwà rere ṣe jẹ́ ìgbé ayé Jésù bí Ó ti ńṣe iṣẹ́ ìránṣẹ́ láárín àwọn ènìyàn. Ó mú okun wá sí ẹsẹ̀ arọ, ìríran sí ojú afọ́jú, gbígbọ́ran sí etí àwọn odi.

Jésù rìn ní ipa àdúrà. Ó kọ́ wa bí a ó ṣe gbàdúrà nípa fífún wa ní àdúrà tí ó rẹwà tí a mọ̀ bí àdúrà Olúwa. Tani ó sì lè gbàgbé àdúrà Rẹ̀ ní Gẹ́tsémánì: "Kìí ṣe ìfẹ́ tèmi, ṣùgbọ́n tìrẹ ni kí á ṣe."[14]

Àwọn àṣẹ míràn tí Olùgbàlà fún wa ní ó wà ní orí ọwọ́ wa, tí a rí nínú àwọn ìwé mímọ́. Nínú ìwàásù Rẹ̀ ní orí Òkè, Ó sọ fún wa pé kí a jẹ́ aláánú, kí á jẹ́ onírẹ̀lẹ̀, kí á jẹ́ olódodo, kí á jẹ́ ọlọ́kàn mímọ́, kí á jẹ́ aláláfíà. Ó pàṣẹ fún wa láti dúró tìgboyà-tìgboyà fún ìgbàgbọ́ wa, àní nígbàtí wọ́n bá ṣe ẹlẹ́yà àti inúnibíni sí wa. Ó bèèrè pé kí a jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ wa tàn kí àwọn míràn lè rí wọn kí wọ́n sì lè ní ìfẹ́ láti yin Bàbá wa ní Ọ̀run lógo. Ó ńkọ́ wa láti jẹ́ oníwà mímọ́ ní èrò àti ìṣe papọ̀. Ó sọ fún wa pé ó ṣe pàtàkì jù láti to awọn ìṣura wa jọ sí ọrun ju ilẹ̀ ayé lọ.[15]

Àwọn òwe Rẹ̀ kọ́ni pẹ̀lú agbára àti àṣẹ. Pẹ̀lú ìròhìn ti ará Samáríà rere, Ó kọ́ wa láti fẹ́ràn àti láti sin àwọn aládúgbò wa.[16] Nínú òwe Rẹ̀ nipa àwọn ẹ̀bùn, Ó kọ́ wa láti mú ara wa gbèrú síi kí a sì tiraka fún ìyege.[17] Pẹ̀lú òwe ti àgùtàn tí ó sọnù, Ó pàṣẹ fún wa láti lọ ṣe gbígba sílẹ̀ àwọn tí wọ́n ti fi ipa ọ̀nà sílẹ̀ tí wọ́n sì ti jùnù ní ọ́nà wọn.[18]

Bí a ṣe ńtiraka láti gbé Krístì sí oókan ìgbé ayé wa nípa kíkọ́ àwọn ọ̀rọ̀ rẹ, nípa títẹ̀lé àwọn ẹ̀kọ́ rẹ̀, àti nípa rírìn ní ipa ọ̀nà Rẹ̀, Ó ti ṣe ìlérí láti ṣe àbápín ìyè ayérayé pẹ̀lú wa tí Ó kú láti jèrè. Kò sí ìparí tí ó ga ju èyí, pé a níláti yàn láti tẹ́wọ́gba ìkora-ẹni-níjánu Rẹ̀ kí a sì di ọmọ ẹ̀hìn Rẹ̀ kí a sì ṣe iṣẹ́ Rẹ̀ ní gbogbo ayé wa. Kò sí ohunkóhun mọ́, kò sí yíyàn míràn tí a ṣe, tí ó lè mú wá di ohun tí Òun lè sọ wá dà.

Bí mo ṣe ńro nipa àwọn tí wọ́n ti tiraka nítòótọ́ láti tẹ̀lé àpẹrẹ Olùgbàlà tí wọ́n sì ti rìn ní ipa ọ̀nà Rẹ̀, ohun tí ó wá sí ọkàn mi lâì ṣe aápọn ni àwọn orúkọ Gustav àti Margarete Wacker — méjì lára àwọn ẹnìkọ̀ọ̀kan tí wọ́n dàbíi Krístì tí mo mọ̀. Wọ́n jẹ́ ọmọ bíbí Gérmánì tí wọ́n ti kó lọ sí ìwọ̀ oòrùn Canada, mo sì pàdé wọn nígbàtí mò ńsìn bí ààrẹ míṣọ̀n níbẹ̀. Arákùnrin Wacker ńgbé ìgbé ayé rẹ̀ bí agẹrun. Bí ó tilẹ̀ jẹ́pé ìní wọn kéré, wọ́n ṣe àbápín gbogbo ohun tí wọ́n ní. Wọn kò ní ìbùkun láti bí àwọn ọmọ, ṣùgbọ́n wọ́n tọ́jú gbogbo àwọn tí wọ́n wọ inú ilé wọn. Àwọn arákùnrin àti arábìnrin onímọ̀-ẹ́kọ́ àti òlàjú máa nwá àwọn onírẹ̀lẹ̀, aláìkàwé ìránṣẹ́ Ọlọrun wọ̀nyí jáde, tí wọ́n a sì máa ka ara wọn sí olórire bí wọ́n bá lè lo wákàtí kan níwájú wọn.

Ìrísí wọn ṣe yẹpẹrẹ, Èdè òyìnbó wọn ńkọsẹ̀ ó sì ṣòro bákan láti yéni, ibùgbé wọn wà ní ìwọ̀ntún-wọnsì. Wọn kò ní ọkọ̀ kankan tàbí ẹ̀rọ amóhùn-máwọ̀rán, tàbí kí wọ́n ṣe ohun kankan nínú àwọn ohun èyí tí ayé máa ńsáábà kọ ibi ara sí. Síbẹ̀síbẹ̀ olódodo ńdé ipa ọ̀nà sí ilẹ̀kùn wọn kí wọn lè ṣe àbápín ẹ̀mí tí ó wà níbẹ̀. Ilé wọn jẹ́ ọ̀run ní orí ilẹ̀ ayé, àti pé ẹ̀mí tí wọ́n ńtàn bí òòrùn jẹ́ ti àláfíà aláìlábàwọ́n àti ìwà rere.

Àwa náà lè ní ẹ̀mí náà kí a sì ṣe àbápín rẹ̀ pẹ̀lú aráyé bí a ṣe ńrìn ní ipa ọ̀nà ti Olùgbàlà tí a sì ńtẹ̀lé àpẹrẹ pípé Rẹ̀.

A ka ìṣílétí nínú àwọn Òwé, "Ronú ipa ọ̀nà ẹsẹ̀ rẹ."[19] Bí a ti ńṣeé, a ó ní ìgbàgbọ́, àní ìfẹ́ náà, láti rìn ní ipa èyí tí Jésù rìn. A kò ní ní iyèméjì pé a wà ní ipa ọ̀nà èyí tí Bàbá wa yíò fẹ́ kí á tẹ̀lé. Àpẹrẹ ti Olùgbàlà pèsè ìlànà iṣẹ́ kan fún gbogbo ohun tí a bá ṣe, àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀ sì ńpèsè ìtọ́sọ́nà tí kìí kùnà. Ipa ọ̀nà Rẹ̀ yíò gbé wá délé láìlewu. Njẹ́ kí èyí jẹ́ ìbùkún wa, mò gbàdúrà, ní orúkọ Jésù Krístì, ẹnití mo fẹ́ràn, ẹnití mò ńsìn, ati nípa ẹnití mo ńjẹ́rìí, àmín.


**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́**
1. Abrahamu 3:25.
2. Lúkù 18:22
3. 3 Nífáì 27:21
4. 3 Nephi 27:27.
5. Eliza R. Snow, "Báwo ni ọgbọ́n náà àti ìfẹ́ náà ṣe pọ̀ tó ," *Hymns,* no. 195.
6. 2 Nífáì 31:16.
7. Lúkù 18:22.
8. Jòhánù 14:6.
9. Lúkù 23:34.
10. Matteu 4:19 Ó sì wí fún wọn pé, Ẹ máa tọ̀ mí lẹ́hìn, èmi ó sọ yín di apẹja ènìyàn .
11. Lúkù 22:44
12. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 29:39.
13. Samuẹli Kíní 15:22.
14. Lúkù 22:42
15. RíMatteu 22:39 Èkejì sì dàbíi rẹ̀, ìwọ fẹ́ ọmọnìkejì rẹ bí ara rẹ
16. Rí Lúkù 10:30–37.
17. Rí Máttéù 25:14–30.
18. Rí Lúkù 15:4–7
19. Proverbs 4:26.

# Àwọn Ekọ́ fún Ìgbà Tiwa

Láti oṣù kẹ́wàá ọdún 2014 sí oṣù kẹrin ọdún 2015, àwọn ẹ̀kọ́ ti Oyè àlùfáà Mẹlkisédékì àti Ẹgbẹ́ Ìrànlọ́wọ́ ní ọjọ ìsinmi kẹ́rin ni a niláti múra rẹ̀ sílẹ̀ láti inú ìkan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ lára àwọn ọ̀rọ̀ Ọlọrun tí a fifúnni ní ìpàdé gbogbogbòò ti oṣù kẹ́wá ọdún 2014. Ní Oṣù Kẹ́rin ọdún 2015, a lè ṣe àṣàyàn àwọn ọ̀rọ̀ bóyá láti inú ìpàdé gbogbogbòò oṣù kẹ́wá ọdún 2014 tàbí oṣù kẹ́rin ọdún 2015. Àwọn Ààrẹ Eèkàn àti Ẹ̀kùn gbọ́dọ̀ yan àwọn ọ̀rọ̀ èyí tí wọn yíò lò ní agbègbè wọn, tàbí wọ́n lè gbé ojúṣe yí lé àwọn Bíṣọ́ọ̀pù àti àwọn ààrẹ ẹ̀ka lọ́wọ́.

Àwọn ọ̀rọ̀ náà wà ní onírũrú èdè ní conference.lds.org.

© 2014 Láti Ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *First Presidency Message, November 2014*. Yoruba. 10871 779



**Láti Ọwọ́ Ààrẹ Dieter F. Uchtdorf**
Olùdámọ̀ràn Kejì Nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Gbígba Ẹ̀rí kan ti Ìmọ́lẹ̀ àti Òtítọ́

*Ẹ̀rí tirẹ lórí ìmọ́lẹ̀ àti òtítọ́ kìí ṣe pé yío bùkún ìwọ àti àwọn àtẹ̀lé rẹ nìkan níhín ní ayé ikú, ṣùgbọ́n ohun yíò tẹ̀lé ọ títí gbogbo ayé àìlópin.*

Gẹ́gẹ́bí atúkọ̀ ọkọ̀ òfúrufú, mo fo ọ̀pọ̀lọpọ̀ wákàtí káàkiri erékùsù ilẹ̀ ayé àti àwọn òkun ní ààrín òkùnkùn ọ̀run. Wíwo ojú ọ̀run lálẹ́ láti ojú fèrèsé atúkọ̀ mi, pàápàá Ọ̀nà Oníwàrà náà, nígbà gbogbo mo máa nní ìyàlẹ́nu lórí gbígbòòrò àti ìjìnlẹ̀ àwọn ohun tí Ọlọ́run dá— tí àwọn ìwé mímọ́ ṣe àpèjúwe bíi "àwọn ayé tí kò lónkà."[1]

Ó kéré ju ọgọ́ọ̀rún ọdún sẹ́hìn tí ọ̀pọ̀ àwọn awòràwọ̀ gbàa lérò pé gálásì ti Ọ̀nà Oníwàrà wa ni gálásì kanṣoṣo ní gbogbo agbáyé.[2] Wọ́n rò pé gbogbo ohun tí ó nà kọjá gálásì wa jẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ àìjẹ́nkankan rárá, òfò àìlópin —asán, òtútù, àti láìsí ìràwọ̀, ìmọ́lẹ̀, àti ìyè.

Bí àwọn dígí ìfiwò ṣe ńdára si—pẹ̀lú àwọn dígí ìfiwò tí a lè jù sínú àlàfo—àwọn awòràwọ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ńní òye, òtítọ́ tí ó fẹ́rẹ̀ má ṣẽ gbàgbọ́: gbogbo àgbáyé le da ìrònú ẹni rú ní tóbi ju ohun tí ẹnìkẹ́ni ti gbàgbọ́ tẹ́lẹ̀, àti pé àwọn ọ̀run kún pẹ̀lú àìlónkà àwọn gálásì, tí a kò lè rò tí ó jìnnà kúrò lọ́dọ̀ wa, ọ̀kọ̀ọ̀kan ní bílíọ̀nù lọ́nà ọgọọ̀gọ́ọ̀rún àwọn ìràwọ̀ nínú.[3]

Ní àsìkò ìgbà tí kò pé jọjọ, ìmọ̀ wa nípa gbogbo ayé yíò yípada títí láé.

Lóní a lè rí díẹ̀ lára àwọn gálásì tí ó jìnnà wọ̀nyí.[4]

A mọ̀ pé wọ́n wà níbẹ̀

Wọ́n ti wà níbẹ̀ fún ìgbà pípẹ́ gidi.

Ṣùgbọ́n ṣíwájú kí ènìyàn tó ní àwọn ohun èlò tí ó ní agbára tó láti kó ìmọ́lẹ̀ cẹ̀lẹ́stíà jọ àti láti mú àwọn gálásì wọ̀nyí wá sí ibi rírí, akò gbàgbọ́ pé irú ohun bẹ́ẹ̀ ṣeéṣe.

àìníwọ̀n gbogbo ayé kò dédé yí padà, ṣùgbọ́n ipá wa láti rí àti láti ní ìmọ̀ òtítọ́ yí yípadà bíi eré. Àti pẹ̀lú ìmọ́lẹ̀ tí ó ga jù náà, wọ́n fi gbogbo ènìyàn hàn sí àwọn ìrí-ìran ológo tí a kò fi ojú inù wò tẹ́lẹ̀ rí rárá.

### Ó Le fún Wa láti Gba Ohun tí A Kò Rí gbọ́

Lérò pé ẹ lè rin ìrìn àjò padà ní àsìkò àti láti ní ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn tí wọ́n gbé ní ẹgbẹ̀rún tàbí ọgọ́ọ̀rún ọdún sẹ́hìn. Fi ojú inú wo títiraka láti ṣe àpèjúwe síwọn díẹ̀ lára àwọn ohun ìgbàlódé tí ẹ̀yin àti èmi ńfi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú lóní. Fún àpẹrẹ, kíni àwọn ènìyàn wọ̀nyí lè rò nípa wa tí a bá sọ àwọn ìtàn ọkọ̀ bàlúù eléré kékeré, ẹ̀rọ amú nkan gbóná, àwọn ẹ̀rọ àfọwọ́mú oní numbà tí ó le kó ìwé pamọ́, àti àwọn móhùn-máwòrán ti àwọn ọmọ ọmọ wa tí a pín lẹ́sẹ̀-kẹsẹ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀ mílíọ̀nù awọn ènìyàn káàkiri àgbáyé?

Àwọn kan lè gbà wá gbọ́. Àwọn púpọ̀ yío ṣẹ̀sín, takò, tàbí bóyá kí wọ́n tilẹ̀ wá láti pa wá lẹ́nu mọ́ tàbí ṣe wá léṣe. Ọ̀pọ̀ lè gbìyànjú láti lo ọgbọ́n inú, èrèdí, àti àwọn òdodo bí wọ́n ṣe mọ̀ọ́ láti fihàn pé à ńgbà ìṣìnà, agọ̀, tàbí pé a léwu. Wọ́n lè dá wa lẹ́bi fún gbígbìyànjú láti ṣì àwọn míràn lọ́nà.

Ṣùgbọ́n ní tòótọ́, yío jẹ́ pé àwọn ènìyàn wọ̀nyí ńṣe àṣìṣe pátápátá. Wọ́n lè ní èrò inú dáadáa àti tòótọ́ Wọ́n lè ní ìmọ̀ara àìyípadà pátápátá nípa èrò wọn. Ṣùgbọ́n wọn kò kàn ní lè ríi ṣákáṣáká nítorí wọn kò tĩ gba ìmọ́lẹ̀ ti òítọ́ tí ó pé dáadáa.

### Ìlérí ti Ìmọ́lẹ̀

Ó dàbíí pé ìhùwà ti ènìyàn ni láti rò pé a tọ̀nà àní nígbàtí a ńṣe àṣìṣe. Ati tí èyí bá jẹ́ bẹ́ẹ̀, kíni ìrètí tí ó wà fún ẹnìkọ̀ọ̀kan lára wa? Njẹ́ ìpín wa ni láti yí kiri láìlérò lórí agbami awọn ìwífúnni tí ń tako ara wọn, kí a tàn sí órí àdìlù tí a tò papọ̀ burúkú láti inú awọn ohun tí a fi ojúṣàjú yàn fún ara wa?

Njẹ́ óṣeéṣe láti rí òtítọ́?

Èrò ọ̀rọ̀ sísọ mi ni láti kéde ọ̀rọ̀ ayọ̀ pé Ọlọ́run Fúnrarẹ̀—Olúwa Awọn Ọmọ Ogun ẹnití ó mọ gbogbo òtítọ́—ti fún àwọn ọmọ Rẹ̀ ní ìlérí pé wọ́n lè mọ òtítọ́ fúnra wọn.

Jọ̀wọ́ ronú jìnlẹ̀ lórí títóbi ìlérí yí:

Ọlọ́run Títíláé àti Alágbára Jùlọ,

Aṣẹ̀dá ayé tí ó gbòòrò yìí, yíò bá gbogbo ẹni tí ó bá dé ọ̀dọ̀ Rẹ̀ pẹ̀lú ọkàn òdodo àti ìdí tòótọ́ sọ̀rọ̀.

Òun yíò bá wọn sọ̀rọ̀ nínú awọn àlá, ìran, èrò, àti ìmọ̀ara.

Òun yíò sọ̀rọ̀ ní ọ̀nà kan tí a kò ní ṣe áṣìṣe rẹ̀ tí yíò sì kọjá ìrírí ti ẹlẹ́ran ara. Òun yíò fún wọn ní ìdarí ti àtọ̀runwá àti àwọn ìdáhùn fún ìgbé ayé ara wọn.

Ní tòótọ́, àwọn wọ̃nnì yíò wà tí wọn yíó kẹ́gàn tí wọn yíò sì sọ pé irú èyí kò ṣeéṣe, pé tí Ọlọ́run kan bá wà, Òun yíò ní àwọn ohun tí ó dára jù láti ṣe ju gbígbọ́ àti dídáhùn àdúrà ẹnìkan ṣoṣo.

Ṣùgbọ́n mo sọ èyí fún yín: Ọlọ́run ńṣe aájò nípa yín. Òun yíò fetísílẹ̀, Òun yíò sì dáhùn àwọn ìbèèrè ti ara yín. Àwọn ìdáhùn sí àwọn àdúrà yín yíò wá ní ọ̀nà ti ara Rẹ̀ àti ní àsìkò ti ara Rẹ̀, àti pé nígbà náà, ẹ̀yin yíò nílò láti kọ́ láti fetísílẹ̀ sí ohùn Rẹ̀. Ọlọ́run ńfẹ́ kí ẹ wá ọ̀nà ara yín padà sí ọ́dọ̀ Rẹ̀, àti pé Olùgbàlà ni ọ̀nà náà.[5] Ọlọ́run ńfẹ́ kí ẹ kọ́ nípa Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, àti kí ẹ sì ní ìrírí àlàfíà tí ó jinlẹ̀ àti ayọ̀ tí ó ńwá nípasẹ̀ títẹ̀lé ipa ọ̀nà àtọ̀runwá ti jíjẹ́ ọmọ ẹ̀hìn.

Ẹ̀yin ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n, èyí ni àṣekọ́ṣẹ́ kan tí ó ṣe tàárà díẹ̀, pẹ̀lú ìfọwọ́sọ̀yà láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, tí a rí nínú ìwé kan ti ìwé mímọ́ àtijọ́ tí ó wà fún gbogbo ọkùnrin, obìnrin, àti ọmọdé tí wọ́n nífẹ́ láti fi í sí ìdánwò.

*Ìkínní,* ẹ gbọ́dọ̀ wá ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Èyí túmọ̀ sí kíka àwọn ìwé mímọ́ àti ṣíṣe àṣàrò lórí àwọn ọ̀rọ̀ àwọn wòlíì àtijọ́ ati ti òde òní bákannáà nípa ìhìnrere ti Jésù Krístì tí a mú-padàbòsípọ̀—kìí ṣe pẹ̀lú ìdí láti ṣiyèméjì tàbí ṣe òfíntótó ṣùgbọ́n pẹ̀lú ìfẹ́ òdodo láti rí òtítọ́. Jíròrò lórí àwọn ohun tí ẹ ti ní ìmọ̀ara, kí ẹ sì múra iyè inú yín sílẹ̀ láti gba òtítọ́ náà.[6] "Àní bí ẹ kò bá le ṣe jù pé kí ẹ fẹ́ lati gbàgbọ́, ẹ jẹ́ kí ìfẹ́ yí ṣiṣẹ́ nínú yín . . . wípé ẹ lè fi àyè sílẹ̀ fun [ọ̀rọ̀ ti Ọlọ́run]."[7]

*Ìkejì,* ẹ gbọ́dọ̀ gbà léro, jíròrò, fi àìbẹ̀rù tiraka láti gbàgbọ́,[8] kí ẹ sì dúpẹ́ fún bí Olúwa ti jẹ́ aláàánú sí àwọn ọmọ Rẹ̀ láti ìgbà ti Ádámù di ọjọ́ tiwa nípa pípèsè àwọn wòlíì, àwọn aríran, àti àwọn olùfihàn láti darí Ìjọ Rẹ̀ àti láti ràn wá lọ́wọ́ láti rí ọ̀nà padà sí ọ́dọ̀ Rẹ̀.

*Ìkẹ́ta,* ẹ gbọ́dọ̀ bèèrè lọ́wọ́ Bàbá yín Ọ̀run, ní orúkọ Ọmọ Rẹ̀, Jésù Krístì, láti fi òtítọ́ Ìjọ Jésù Krístì ti àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́-ìkẹhìn hàn síi yín. Bèèrè pẹ̀lú ọkàn òdodo àti pẹ̀lú ìdí tí ó dájú, níní ìgbàgbọ́ nínú Krístì.[9]

Ìṣísẹ̀ *kẹ́rin* wà bákannáà, tí Olùgbàlà fi fún wa: "Tí ẹnìkẹ́ni yíò bá ṣe ìfẹ́ [ti Ọlọ́run], òun yíò mọ ẹ̀kọ́, bóyá ti Ọlọ́run ni, tàbí bóyá mo sọọ́ fúnra mi."[10] Ní ọ̀rọ̀ míràn, nígbàtí a bá ńgbìyànjú láti wádí òtítọ́ ti àwọn ìpìlẹ̀ ẹ̀kọ́ ìhìnrere, ẹ gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ gbé ìgbé ayé wọn. Ẹ gbé ẹ̀kọ́ ìhìnrere àti àwọn ìkẹ́kọ́ Ìjọ sí ìdánwò nínú ayé yin. Ṣeé pẹ̀lú ìdí tí ó dájú àti ìfaradà ìgbágbọ́ nínú Ọlọ́run.

Bí ẹ̀yin yíò bá ṣe àwọn ohun wọ̀nyí, ẹ ní ìlérí kan láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ẹnití ó jẹ́ dídè nípa ọ̀rọ̀ Rẹ̀[11]—wípé Òun yíò fi òtítọ́ hàn síi yín nípa agbára ti Ẹ̀mí Mímọ́. Òun yíò fi ìmọ́lẹ̀ gíga jù fún yín tí yíò gbà yín láàyè láti wo inú òkùnkùn kí ẹ sì jẹ́rí ìrí-ìran ológo àìlèrò àìlóye sí ìríran ayé ikú.

Ọ̀pọ̀ lè sọ pé àwọn ìṣísẹ̀ wọ̀nyí ti le jù tàbí pé kò tọ́ kí wọ́n gbìyànjú. Ṣùgbọ́n mo dá àbá pé ẹ̀rí ti ara-ẹni yí nípa ìhìnrere àti Ìjọ ní ohun tí ó ṣe pàtàkì jù tí a lè gbà ní ayé yí. Kò ní bùkún ayé yín nìkan àti kí ó tọ́ọ yín sọ́nà nínú ayé yí, ṣùgbọ́n bákannáà yíò ní ìdarí tàárà lórí ayé yín ní gbogbo ayérayé.

### Àwọn Ohun ti Ẹ̀mí Le Yéni nípa Ẹ̀mí Nìkan

Àwọn onímọ̀ Síyẹ́nsì ńtiraka láti ní ìmọ̀ ìbú gbogbo ayé títí tí àwọn ohun èlò fi dára si tó láti kó wọ́n jọ nínú ìmọ́lẹ̀ tí ó tóbi jù kí wọ́n lè ní ìmọ̀ pípé òtítọ́ síi.

Àpọ́stélì Páùlù kọ́ni ní ẹ̀kọ́ ìpìlẹ̀ ọgbọọgba nípa ìmọ̀ ti ẹ̀mí. "Ẹ̀nìyàn ẹlẹ́ran ara kò lè gba àwọn ohun ti Ẹ̀mí Ọlọ́run," ó kọ sí àwọn ara Kọ́ríntì, "nítorí ó jẹ́ àìlọ́gbọ́ sí i: bẹ́ẹ̀ni kò lè mọ̀ wọ́n, nítorí wọ́n jẹ́ òye ti ẹ̀mí."[12]

Ní ọ̀rọ̀ míràn, tí ẹ bá fẹ́ láti mọ òtítọ́ ti ẹ̀mí, ẹ níláti lo àwọn ohun èlò tó tọ́. Ẹ kò lè wá sí níní òye òtítọ́ ti ẹ̀mí pẹ̀lú àwọn ohun èlò tí kò lè wá a rí.

Olùgbàlà ti sọ fún wa ní ọjọ́ wa, "Èyí nì tí íṣe ti Ọlọ́run jẹ́ ìmọ́lẹ̀, ẹni tí ó bá sì gbà ìmọ́lẹ̀, tí ó sì ńtẹ̀síwájú nínú Ọlọ́run, ńgba ìmọ́lẹ̀ sí i, ìmọ́lẹ̀ náà sì ńdàgbà síwájú àti síwájú sí i títí di òpin ọjọ́."[13]

Bí a bá ṣe ńfi ọkàn àti iyè inú wá síwájú Ọlọ́run síi, ní ìmọ́lẹ̀ ọ̀run yíò má kán lé orí ẹ̀mí wa sí. Àti pé ìgbà kọ̀ọ̀kan tí a bá fi tìfẹ́tìfẹ́ àti akitiyan ṣe àwárí ìmọ́lẹ̀ náà, à ńfi ṣíṣetán wa hàn Ọlọ́run láti gba ìmọ́lẹ̀ sí i. Díẹ̀díẹ̀, àwọn ohun tí ó dàbí pé ó ni íkukù, ṣókùnkùn, tí ó sì jìnnà yíò di kedere, mímọ́lẹ̀, àti bíbámu sí wa.

Nípa àmì kannáà, tí a bá mú ara wa kúrò nínú ìmọ́lẹ̀ ìhìnrere, ìmọ́lẹ̀ tiwa yíò bẹ̀rẹ̀sí ńṣókùnkùn—kìí ṣe ní ọjọ́ kan tàbí ọ̀sẹ̀ kan ṣùgbọ́n díẹ̀díẹ̀ bí ìgbà ti ńlọ títí tí a ó fi wo ẹ̀hìn tí a kò ní lè ní ìmọ̀ ìdí tí a gbàgbọ́ rárá pé ìhìnrere jẹ́ òtítọ́. Ìmọ̀ wa tẹ́lẹ̀ lè ti dàbí àìgbọ́n sí wa nítorí ohun ti ó ti fi ìgbà kan hàn kedere ti di ṣíṣú lẹ́ẹ̀kansi, ní kuùkù, àti jíjìnnà.

Èyí ni ìdí tí Páùlù ṣe tẹnumọ pé ọ̀rọ̀ ti ìhìnrere jẹ́ àìlọ́gbọ́n sí àwọn ẹni tí ó ńṣègbé, "ṣùgbọ́n sí [àwọn wọnnì] tí a gbàlà ó jẹ́ agbára Ọlọ́run."[14]

### Kò sí Ìdánwò Lítmúsì Kankan

Ìjọ Jésù Krístì ti Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́-ìkẹhìn jẹ́ ibì kan fún àwọn ènìyàn pẹ̀lú gbogbo onírurú àwọn ẹ̀rí. Àwọn ọmọ ìjọ díẹ̀ wà tí àwọn ẹ̀rí wọn dájú tí ó sì ńjó dídán nínú wọn. Àwọn míràn ṣì ńtiraka síbẹ̀ láti mọ fúnra wọn. Ìjọ náà jẹ́ ilé fún ẹni gbogbo láti wá papọ̀, láìka jíjìn tàbí gígùn ti ẹ̀rí wa sí. Èmi kò mọ àmì kankan lẹ́nu ọ̀nà àwọn ilé ìpàdé wa tí ó sọ pé, "Ẹ̀rí yín gbọ́dọ̀ gùn tó báyìí kí ẹ tó wolé."

Ìjọ náà kìí ṣe fún àwọn ènìyàn pípé, ṣùgbọ́n fún ẹni gbogbo láti "wá sí ọ́dọ̀ Krístì, kí a sì di pípé nínú rẹ̀."[15] Ìjọ náà jẹ́ fún àwọn ènìyàn bí tìrẹ àti èmi. Ìjọ náà jẹ́ ibì ṣíṣe ìkíni káàbọ̀ ati ìtọ́jú, kìí ṣe ibi ṣíṣe ìyapa tàbí òfíntótó. Ó jẹ́ ibì kan tí a ti ńawọ́ jáde láti gbani níyànjú, gbéni sókè, kí a sì ṣe ìmúdúró ara wa bí a ṣe ńlépa ṣíṣe àwárí òtítọ́ àmútọ̀runwá bĩ ẹnìkọ̀ọ̀kan.

Ní ìparí, gbogbo wa jẹ́ arìnrìn àjò tí ó ńṣe àwárí ìmọ́lẹ̀ ti Ọlọ́run bí a ṣe

ńrìn ìrìn àjò ní ipa ọ̀nà ti ọmọlẹ́hìn. A kò dá àwọn ẹlòmíràn lẹ́bi fún iye ìmọ́lẹ̀ tí wọ́n lè ní tàbí tí wọn kò ní, kàkà bẹ́ẹ̀, à ńtọ́jú à sì ńgbà gbogbo ìmọ́lẹ̀ níyànjú títí yíò fi dàgbà kedere, di dídán, àti jẹ́ òótọ́.

## Ìlérí kan sí Ẹni Gbogbo

Ẹ jẹ́ kí a jẹ́wọ́ pé nígbà gbogbo jíjèrè ẹ̀rí kìí ṣe iṣẹ́ ìṣẹ́jú kan, wákàtí kan, tàbí ọjọ́ kan. Kìí ṣe ẹ̀ẹ̀kan kí ó sì ṣe. Ètò ti kíkó ìmọ́lẹ̀ ẹ̀mí jọ jẹ́ ìwákiri fun gbogbo ìgbé ayé.

Ẹ̀rí yín nípa Ọmọ Ọlọ́run alààyè àti ìmúpadàbọ̀sípò Ìjọ Rẹ̀, Ìjọ Jésù Krístì ti àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́-ìkẹhìn, lè má wá kíákíá bí ẹ ṣe fẹ́, ṣùgbọ́n mo ṣelérí fún yín pé: Bí ẹ bá ṣe ipá yín, yíò wá.

Yíò sì jẹ́ ológo.

Mo fún yín ní ẹ̀rí ti ara mi pé òtítọ́ ti ẹ̀mí yíò kún ọkàn yín yíò sì mú ìmọ́lẹ̀ wá sí ẹ̀mí yín. Yíò fi òye mímọ́ hàn yín pẹ̀lú ayọ̀ ìyanu àti àláfíà tọ̀run. Mo ti ní ìrírí èyí fúnra mi nípa agbára ti Ẹ̀mí Mímọ́.

Gẹ́gẹ́bí àwọn ìwé mímọ́ àtijọ́ ti ṣèlérí, àìlèsọ ti wíwà Ẹ̀mí Ọlọ́run yíò mú kí ẹ kọ orin ti ìfẹ́ ìràpadà,[16] gbé ojú yín sókè sí ọ̀run, àti gbígbé ohùn yín sókè ní ìyìn sí Ọlọ́run Gíga Jùlọ, Ààbò yín, Ìrètí yín, Olùdáàbòbò yín, Bàbá yín. Olùgbàlà ṣèlérí pé tí ẹ bá wákiri ẹ̀yín ó rí.[17]

Mo jẹ́rĩ pé èyí jẹ́ òtítọ́. Bí ẹ bá wá òtítọ́ ti Ọlọ́run, èyí tí ó lè dàbíi pé ó ńṣókùnkùn, kúrò ní ìdojúkọ, àti jíjìnnà yíò farahàn díẹ̀díẹ̀ yíò dá ṣáká yíò sì súnmọ́ ọkàn rẹ nípa ìmọ́lẹ̀ ti oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run. Àwọn ìrí-ìran ológo ti ẹ̀mí, àlàìṣe fi ojú inú wò ní ojú ẹlẹ́ran ara, yíò hàn síi yín.

Ó jẹ́ ẹ̀rí mi pé ìmọ́lẹ̀ ti ẹ̀mí yí wà ní àrọ́wọ́tó ọ̀kọ̀ọ̀kan ọmọ Ọlọ́run. Òun yíò la iyè inú yín lóye yíò sì mú ìwòsàn wá sí ọkàn yin àti ayọ̀ sí àwọn ọjọ́ yin. Ẹ̀yin ọ̀rẹ́ mi ọ̀wọ́n, ẹ jọ̀wọ́ ẹ máṣe jáfara àsìkò láti wá kiri àti láti fún ẹ̀rí ti ara yin lókun nípa iṣẹ́ ọ̀run ti Ọ̀lọ́run, ání iṣẹ́ ìmọ́lẹ̀ àti òtítọ́.

Ẹ̀rí ati ara yin nípa ìmọ́lẹ̀ àti òtítọ́ kì yíò bùkún ẹyin nìkan àti àtẹ̀lé yin níhín ní ayé ikú, ṣùgbọ́n yíò tẹ̀lé yin bákannáà ní gbogbo ayé àìnípẹ̀kun, ní ààrín àwọn ayé láìní òpin. Nípa èyí ni mo jẹ́rí tí mo sì fi ìbùkún mi sílẹ̀ fún yín ní orúkọ Jésù Krístì, àmín.

### ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́

1. Mósè 1:33
2. Rí Marcia Bartusiak, *The Day We Found the Universe* (2009), xii. Ó ńfigbàgbogbo yà mí lẹ́nu pé a lè ní ìdánilójú ti ìparí ara wa gan an. Ní àwọn ìgbà míràn ìgbékẹ̀lé tiwa pọ̀ gidi tí a fi ńṣèbí a ní gbogbo òtítọ́ tí ó wà Àmì tó wà ní ẹ́jọ́: “Simon Newcomb, Olórí ti American astronomy ní cẹ́ntúrì mọ́kàndínlógún, sọ̀rọ̀ ní ibi àkíyèsí ìyàsímímọ́ ní ọdún 1887 tí ó jẹ́ pé bí ìwòràwọ̀ ti jẹ́ . . . à ńdà bíi pé a ti ńdé òpin ti òye wa. . . . àbájáde náà ni wípé iṣẹ́ náà èyí tí ó ńgba ìtẹ́tísílẹ̀ ti awòràwọ̀ nàà kéréju àwárí ti àwọn ohun titun tó ju fífẹ̀ ti àwọn tí a mọ̀ tẹ́lẹ̀’ ”(Bartusiak, xv).
3. Ó lárinrin láti gbèrò Mósè 1:33, 35 nínú ìmọ́lẹ̀ ti àwárí “àìpẹ́” yí. Ìwé mósè nínú Pẹ́árlì Iyebíye ni wọ́n fihan Wòlíì Joseph Smith ní Oṣù Kẹ́fà Ọdún 1830, ní bíi ọgọ́ọ̀rún ọdún ṣẹ́hìn ṣíwájú ìkéde àwárí ti Edwin Hubble nípa àwọn gálázì ọ̀nà jínjìn.
4. Rí, fún àpẹrẹ, àkójọ àwòrán ogun Hubble ní heritage.stsci.edu/gallery/gallery.html.
5. Rí Jòhánù 6:66
6. Rí 3 Nífáì 17:3
7. Álmà 32:27
8. Wo Ẹ̀kọ́ àti àwọn májẹ̀mú 84:20
9. See Moroni 10:3 Ẹ kíyèsíi, ẹ̀mí yíò rọ̀ yín pé nígbàtí ẹ̀yin yíò bá kà àwọn ohun wọ̀nyí, bí ó bá jẹ́ ọgbọ́n nínú Ọlọ́run pé kí ẹ̀yin ó kà wọ́n, pé ẹ̀yin ó rántí bí Olúwa ti ní àánú tó sí àwọn ọmọ ènìyàn, láti ìgbà dídá Ádámù àní títí dé ìgbà tí ẹ̀yin yíò rí àwọn ohun wọ̀nyí gbà, kí ẹ sì ṣe àṣàrò lórí rẹ̀ nínú ọkàn yín.–5.
10. Jòhánù 7:17; rí Ìwé orin Dáfídì bákannáà 25:14; Jòhánù 3:21
11. Wo Ẹ̀kọ́ àti àwọn Májẹ̀mú 84:20
12. 1 Kọ́ríntì 2:14 Ṣùgbọ́n ènìyàn nípa ti ara kò gbà ohùn ti Ẹ̀mí Ọlọ́run wọnnì: nítorípé wèrè ni ńwọn jásí fún un: òun kò sì lè mọ̀ wọ́n, nítorí nípa ti Ẹ̀mí ni a fi ńwádí wọn.gbọ́
13. Ẹ̀kọ́ àti Àwọn Májẹ̀mú 59:2
14. 1 Kóríntì 1:18 Nírotípé wèrè ni ọ̀rọ̀ àgbélébú sí àwọn tí ó ńṣègbé; ṣùgbọ́n sí àwà tí à ńgbàlà, agbára Ọlọ́run ni.
15. Mórónì 10:32 Bẹ́ẹ̀ni, ẹ wá wí ọ̀dọ̀ Krístì, kí a sì sọ yín di pípé nínú rẹ̀, kí ẹ sì sẹ́ ara yín ní ti gbogbo àìwà bí Ọlọ́run; bí ẹ̀yin bá sì sẹ́ ara yín ní ti gbogbo àìwà bí Ọlọ́run, àti kí ẹ sì fẹ́ Ọlọ́run pẹ̀lú gbogbo agbára, iyè àti ipá yín, nígbànáà ni oore ọ̀fẹ́ rẹ̀ sì tó fún yín, pé nípa oore ọ̀fẹ́ rẹ̀ ẹ̀yin lè di pípé nínú Krístì, àti nípa oore ọ̀fẹ́ Ọlọ́run bí ẹ̀yin bá di pípé nínú Krístì, ẹ̀yin kò lè sẹ́ agbára Ọlọ́run.; rí Doctrine and Covenants 20:59 bákannáà.
16. Rí Álmà 5:26 Àti nísisìnyí kíyèsíi, mo wí fún un yín, ẹ̀yin arákùnrin mi tí ẹ̀yin bá ti rí ìyípadà ọkàn, tí ẹ̀yin bá sí fẹ́ láti kọ orin ìfẹ́ ti ìràpadà, mo bèèrè, njẹ́ ẹ̀yin sì fẹ́ bẹ́ẹ̀ bí?
17. Wo Doctrine and Covenants 84:20

© 2014 Láti Ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/14. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/14.
Ìtumọ̀ ti *Visiting Teaching Message, November 2014*. Yoruba. 10871 779